# Irohin Yoruba

ẸṢIN ỌRỌ WA:—IWAJU L'ỌPA EBITI NRE SI
Fun owo "Irohin Yoruba" ọdun kan
Eko—ṣile mẹjọ ati kobo mẹjọ (8s. 8d.)
Ilu miran ni Nigeria ati Oke Okun ṣile mẹtala (13s.)


## ỌRỌ-OLOTU

## Ọdun 1958 nkọja lọ

## Siro iṣẹ iriju rẹ

ENYIN enia gbogbo kakiri igun mẹrẹrin agbaiye, a fẹ ran nyin leti pe Ọdun 1958 nrekọja lọ si opin nisisiyi, ti o ba di ọjọ marun a o ma a ki ara wa ku ewu ọdun titun.

OHUN pataki ti a fẹ pe akiyesi gbogbo ẹnyin onkawe wa si ni lati bojuwo ẹhin lati ṣiro iwa wa lati bẹrẹ ọdun na titi o fi de opin yi, ere ni a jẹ ni tabi adanu?

NIGBATI ọdun ba nlọ si opin bayi, awọn oniṣowo a ma a yara kankan ṣiro gbogbo ọja wọn lati mọ iye ere ti nwọn jẹ lati ibẹrẹ ọdun na titi de opin rẹ. Ọja ti nwọn ba ri i pe yio di ẹti si wọn lọrun ninu Ṣọpu, nwon a tete lu u ni gbanjo.

ṢUGBỌN ohun ti awa nran nyin leti nihin lati fi mọ bi a jere ni tabi a adanu ni, ki iṣe lori iṣẹ owo bikoṣe lori iwa.

ỌNA ti a le fi mọ pe a jere niyi, lati igbati ọdun ti bẹrẹ elo ni owo tabi ohun-ini ti a ti fi ta awọn alagbe lọrẹ, enia mẹlo ni a ṣe iranwọ fun lati ma a ri onjẹ ọjọ jẹ enia melo ni a ti fi iwa rere wa yi ni ọkan pada kuro ninu ibi, enia mẹlo ni a t ṣe ore fun ti a ko ni ireti a ti gba inkan-kan pada lọwọ wọn?

TI a ba le ri ọpọlọpọ juwe ki a mọ daju pe ọpọlọpọ ni ere ti a jẹ ni ọdunni nitoripe ko si ere ti enia le jẹ laiye ju ki ọpọlọpọ awọn ti a ti ṣe inu rere fun ma a sure fun wa lo.

ṢUGBỌN ẹniti o wa idi ọkan rẹ wo ti o ri i pe, gbogbo irinsi on lati bẹrẹ ọdun na ti o fi nlọ si opin yi ko san ju ti alọnilọwọgba lọ, ki oluwarẹ mọ pe adanu ni gbogbo laala on ati ibẹrẹ ọdun na de opin nitori ile ti a fi itọ mọ iri ni yo wo o, ọrọ ti a fi eru kojọ ko le pẹ titi.

KI awa tun ronu wo wayi, ki a wo awọn ti ajijọ bẹrẹ ọdun na ṣugbọn nisisiyi nwọn ti sun ni iboji, laini iret, ara wọn si pada si erupẹ, ẹmi awọn ti o jere pada to Ọlọrun lọ, ẹmi awọn ti o padanu lọ sinu okunkun-biribiri nibiti ẹkun ati ipa-ehin-keke gbe wa, ki Ọlọrun maṣe wa ni ẹni ọrun apandi lẹhin iku o.

KI awa paapa wa ranti pe, wakati kan mbọ ni arin ọjọ kan larin ọsẹ kan ninu oṣu kan ninu ọdun kan ti a o di "oku" tabi "Oluogbe". Bi a ko tilẹ ti mọ akoko ati igba na, o yẹ ki a mura silẹ ni gbogbo ọjọ pe, "a ti wa". "Gbogbo igba, ẹ wa ni imura-silẹ".

ẸDA ti o ba sọ pe, on ti to tan, on ti mọ tan on ko tun fẹ imọran ẹnikan mọ, ki o mọ daju pe, oferefe ni on wa, ohun ti iru ẹni bẹ ẹ gb'ojule ni ọdunni, o le di omulẹmofo ni ọla, iyẹn ni o mu ki awọn agbalagba fi ma a npa owo pe, "Bi oni yio ti ri, ọla ki i ri bẹ ẹ, ni o ngmu Babalawo fi da ifa ororun."

NITORINA, ẹniti o ba ti ri ọpọlọpọ ayọ, inu-didun ati alafia ninu ọdun yi ki o maṣe lero pe, mimọṣe on ni, ko si ẹniti o gbọn af'Ọlọrun, Ọba na ti o ti ri iwaju, ti o ti ri ẹhin ti o s mọ aye ti yio to olukuluku wa si ninu ọdun ti mbọ yi ko si aṣiṣe ni ọwọ Rẹ.

NI ipari ọrọ iyanju wa fun ipari ọdun 1958, ẹ jẹki a ranti awọn asayan ọrọ wonyi lati inu Bibeli, ki o le jẹ eegbogi iṣọra fun wa de inu ọdun titun.

BAYI ni Oluwa wi, "Ki ọlọgbọn ki o maṣe ṣogo ninu ọgbọn rẹ, bẹni ki alagbara ki o maṣe ṣogo ninu agbara rẹ. Ṣugbọn ki ẹnikẹni ti yio ba ma a ṣogo, ki o ṣe e ninu eyi pe, on ni oye, on si mọ Mi" pe, "Emi ni Oluwa ti nṣe anu ati idajọ ati ododo ni aiye." Jeremia 9: 23 de 24. Ekeji si dabi rẹ, ti o wipe:—Ẹre kini fun enia, bi o le jere gbogbo aiye, ti o si sọ ẹmi ara rẹ nu? Matte 16: 26.

KI ọdun na to kọja, ẹ jẹki a bẹ Ọlọrun, ki O ran wa lọwọ ki a tubọ ma a pẹ si i ninu iṣẹ rere ki a le ma a ri iyẹnu Ọlọrun gba ni gbogboigba, ki O si pẹlu wa wọ inu ọdun 1959. Amin.



## Alakukọ dapọmọ Olomi

*Lati oju ewe kini*

O ni ti awọn Aṣiwaju Ẹgbẹ Olomi NPC ni pe, nwọn a ma a fi ope wọn pamọ, nwọn ko ni imọ Ipinlẹ Iṣelu, nwọn ko si fẹ ki gbogbo awọn enia Ipinlẹ Ariwa ri aṣiri yi ni, nwọn ko si fẹ ki onikaluku Ẹgbẹ Oṣelu sọrọ pẹlu alafia ni Ipinlẹ Ariwa ṣugbọn nisisiyi aye ti wa fun olukuluku Ẹgbẹ Oṣelu lati ṣe ipade ati lati sọrọ lalafia nisisiyi, nitorina o ni on yio ma a wa si Ipinlẹ Ariwa nisisiyi lati ma a wa ṣe ipade ati ikede ibo ti aṣeko idibo ba to.

O ni gbogbo alafia ti awọn enia Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ni awọn nfẹ ki awọn enia Ipinlẹ Ariwa paapa ni. O ni ki nwọn le mọ bi igbega ti nwa fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre si, ati bi irẹ-nlẹ ti mba Ẹgbẹ Alakukọ si, ibo ti nwọn di laipẹ yan aṣoju si Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ni Oyọ ati Ado-Ekiti, Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o bori ni ilu mejeji.




# AWORAN ONITAN






# Bi Ori Ba pẹ ni'lẹ A D'ire

## Lati ọwọ E. Alabi Thompson, Lagos

OLOTU ati gbogbo onkawe "Irohin Yoruba" mo fi tayọtayọ ki nyin ku ọdun, ẹ ku iyedun, Oluwa ko ṣe ọdun l'abo. Agan a ṣiṣẹ ebi ẹni ti bi a jere ọmọ, eni ti ko ti i bi a r'ọmọ gbejo, ọmọ rere a gbẹhin gbobo wa o. Amin.

O tọ o si yẹ lati ba ara wa sọ asọye pọ. Nipa ṣiṣe eyi, ogbọn ori ati ẹkọ iyebiye ti a nri gba nipa kika iwe "Irohin Yoruba" yio tubọ ma a lọ siwaju.

Ni igba lailai, ọkunrin kan wa oruko rẹ a ma a je "Ọmọbola" anijẹ tabi oruko inagijẹ ti nwọn tun npe e ni "Bi ori pẹ n'ilẹ a d'ire". Oriki ọmọkunrin yi gbilẹ ni ilu, o si gbajumọ pupọ. Ṣugbọn inawo nla kan yọ si i eyiti o mu u lati lọ ko owo ogoji-ọkẹ ti o si nsingba rẹ. Ti o ba bere ni afẹmojumọ a pari iṣẹ nigbati orun tanmọ s'oko ba yọ. O sin iru yi fun ọdun meji ati abo.

Nigbati o de oko ni ọjọ kan, bi o ti nro oko lọ ni ọkọ rẹ ṣa ikoko nla kan ti nwọn ti ri imọlẹ ni ọjọ pipe, nigbati o si ọmọri ikoko na kuro, o ri i wipe owo idẹ ni o kun inu ikoko yi. O gbe ikoko na o si da owo inu rẹ silẹ, o ka a, gbogbo owo na jẹ ọgorun ọkẹ (£25).

Lojukanna orişirişi ero bọ sinu rẹ, yalaa ki on mu ninu rẹ lọ fi san owo ẹgba ti o nsin ki o si ma a lọ lo iyoku fun anfani ara rẹ. Lọna keji ọkan kan sọ fun un wipe ki o ṣe otitọ nipa fifi owo na fun baba oloko ti o nsingba lọdọ rẹ.

Ero yi ni o bori ọkan rẹ. o ko owo yi o fi fun oloko, oloko yi wo o tika-tẹgbin, o gba owo na lọwọ rẹ, o ju ṣile kan pere si i o si wi fun un pe "eleyi fi han wipe iwọ ko le bọ ninu iṣẹ lailai".

Gbara ti o bọ sinu ilu ni irohin ti kan kakiri wipe "Bi ori ba pẹ n'ilẹ a d'ire" ri owo he, o si gbe e lọ fun Ọga rẹ; Iwa bayi mu ki gbobo enia bẹrẹsi pẹgan rẹ, nwọn si bẹrẹsi sọrọ aidara si i pe, o gọ pupọ ju, awọn ẹlomiran bẹrẹsi fi ṣẹfẹ awọn obirin si bẹrẹsi fi da apara, nwọn si nkọrin bu u, iyawo rẹ si bẹrẹsi bu u ni orişirisi eebu tobẹẹ ti o fi su okunrin yi.



E. ALABI THOMPSON

* * *

Ni ọjọ kan bi ọkunrin yi ti nrin kakiri taanu-taanu ni o pade abami-'enia kan ni oju ọna, abami enia na si da a uro lati bere ohun ti o ṣe e ti o fi nrin taanutaanu kakiri. Nigbati o sọ gbogbo ẹdun ọkan rẹ fun un tan, ni enia-abami na ba towọ bọ apo o si fun un lowo pe ki o lọ sanwo ẹgba ti o nsin, o si kilọ fun un pe ki o jade ni ilu, ọkunrin akuşẹ yi san owo f'olowo o di ẹru rẹ, o si jade kuro ni ilu na pẹlu iyawo rẹ gẹgẹbi ikilọ ti enia-abami na ṣe fun un.

Ninu ilu titun ti o de yi, o pinnu ni ọkan rẹ lati ma a ṣiṣẹ aponmi-ta. Ọba ilu titun ti o lọ yi ṣe oninure pupọ, ṣugbọn bi o ti wu ki enia ni inurere to, ko da iku duro, ni ọjọ ti o ba ya iku ti yio mu oluware lọ. Aiṣan kọ lu Ọba yi, laipẹ ọjọ, Oba yi ku; gbogbo ilu si ṣofo re pupọ nitoripe tile-toko ni o mọ riri iwa inurere Oba yi.

Lẹhin eyi gbogbo awọn Ọlọtọ ilu pejọ, nwọn si pinnu lati da Ifa, ki o fi han wọn bi awon yio ti ṣe le ri oninurere enia ni ilu lati fi je ọba, ẹniti ọmọluwabi rẹ yio koja ariyanjiyan.

Nwọn da Ifa, Ifa yọ si wọn wipe ki nwọn pe gbogbo awọn aponmita ni ilu, ki nwọn pin ladugbo omi fun wọn lati pọn omi si agbala ọba. Eyiti oba ba ye ti o si to si yio fi ara re han. Lọgan, nwọn gbe agogo sita lati pe gbogbo awọn aponmi-ta lati lọ pọn omi si agbala ọba.

Ọmọbọla 'Bi ori ba pẹ n'ilẹ a d'ire" wa ninu wọn. Nwọn pin ladugbo le wọn lọwọ. Ṣugbọn ninu ladugbo kọọkan, nwọn fi ọkẹ merin-merin owo sinu ọkọọkan.

Gbogbo awọn aponmi-ta wọnyi ri owo ti nwọn fi pamọ yi, nwọn si yọ o pamọ. Şugbọn nigbati Ọmọbọla ri owo yi, ọkan rẹ ko balẹ, lojukanna o bẹrẹsi ronu wipe, bi on ba fi owo na jiṣẹ, nwọn o pe on ni omugọ, nwọn o fi on kọrin

Wo oju ewe kejo



# Awọn ohun pataki ti o ṣẹlẹ ninu Ọdun 1958

## JANUARY

[illegible]

## FEBRUARY

[illegible]

## MARCH

[illegible]

## APRIL

[illegible]

## MAY

[illegible]

## JUNE

[illegible]

## JULY

[illegible]

## AUGUST

[illegible]

## SEPTEMBER

[illegible]

## OCTOBER

[illegible]

(Wa ojo iwe keji)





L'aro
Andrews

[illegible]

O DUN-LENU
O nta Wọnin-Wọnin . . . O Ntẹjẹsi




[illegible]


Ohun Orin ti o le mu inu rẹ dun




PHILIPS
'West African' RECORDS

PHILIPS (WA) LTD, P.M.B. 2023, LAGOS



OLOGBON AGBẸ
NGUN RALEIGH




Pelu irọrun ni ologbon
agbẹ ngun Raleigh de'bi
ise. Ko gba'gbara,
ko gba'siko, nitorina
o le ko ebe lopolopo,
ko si gbin ohun ọgbin
pelu. O nko ohun jọ
lo oja lati s'ataru.
Nipa bẹ yio ma pawo pupọ.

O GBODO gun Raleigh

GBOGBO IRIN KEKE
RALEIGH
LO RO

# Işęlę Ọdun 1958

*Lati oju ewe kefa*

Port Harcourt gbe Dominic Okoye ti o wa ninu ipo keta ninu işe olopa (third class Police Constable) lọ.

Ni ọjọ Aje ti işe ogunjọ oşu yi ni Ọba'birin Gęęsi gba awọn Aşiwaju Oşelu Naijiria lalejo.

Ni ọjọ Işegun ti işe oşu yi ni Igbimọ Ipade Londonu bęrę Ipade.

Ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kọkanlelogun oşu yi ni ija-igboro bęsilę larin enia dudu pęlu Oyinbo ni Londonu.

Ni ọjọ Abamęta ti işe ọjọ kedogun oşu yi ni Ogbęni Alan Lennox Boyd, Aşoju Ijọba Gęęsi fun awọn ilu abę akoso Ijọba Gęęsi jişę Ọlọlajulọ Alaiyeluwa Elizabeth Keji fun awọn iko Naijiria ti nwọn lọ şe Ipade Londonu pe nwọn yio fun Apapọ Ijọba Naijiria ni Ominira ni ọjọ kini oşu kewa ọdun 1960.

## NOVEMBER

Ni ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ karun oşu yi ni Oloye Ọbafęmi Awolowọ, Alakoso Ijọba Ipinlę Iwọ-Orun ba ọkọ ofurufu gunlę si Ebutę Ikęja l'Eko lati ilu Londonu ti o ti lọ bi ọsę meje fun Ipade Londonu.

Ni ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kętadinlogbon oşu yi ni awọn ọmọ Ęgbę Oduduwa bęrę Ipade Ajọdun kọkanla.

Ni ọjọ Işegun ti işe ọjọ kedogbon oşu yi ni awọn Igbimọ Atọni-sọna ti General Medical Council Londọnu yọ orukọ Dokita Joseph Adewunmi Ademiluyi ọmọ Naijiria kuro ninu iwe Ęgbę Onişegun.

Ni ọjọ Işegun ti işe ọjọ kejidilọgbọn oşu yi ni Ijọ Aguda Ilu Vatican yan Cardinal Angelo Giuseppe Rancalli eni ọdun mętadinladọrin ti işe Alakoso Ijọ Ilu Venice ni Popu titun rọpọ Ęnimimọ-julọ Pope Pius Kejila ti o ku.

## DECEMBER

Ni ọjọ Aje ti işe ọjọ kini oşu ...yi ni Ipinlę Iwọ-Orun şe Ajọdun kini ti nwọn ti gba Ominira Ijọba.

Ni ọjọ Işegun ti işe ọjọ keji oşu yi ni Igbimọ Ijọba Ipinlę Iwọ-Orun f'owọ si ọjọ Ominira Ijọba Apapọ Naijiria.

Ni ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kęrin oşu yi ni Ọba Alaiyeluwa C. D. Akran wuye.

Ni ọjọ Abamęta ti işe ọjọ kęfa oşu yi ni Ijọba Ghana le Ayọọla kuro nilu lojiji.

Ni ọjọ 'Ru ti işe ọjọ kewa oşu yi ni awọn ara Ipinlę Ariwa f'eyę nla pade Awolowọ.

Ni ọjọ 'Ru ti işe ọjọ kewa oşu yi ni Ogbęni S. O. Shonibare, Akọwe Apapọ Ęgbę Afenifere ni Ęgbę NEPU ni lati tę wọrọkọ tabi ki o şe.

# Bi ori ba pę ni ilę A Di ire

**(Lati oju ewe karun)**

eebu kakiri ilu, şugbọn ọkan rę tun sọ fun un ni idakeji pe ki o mu owo yi lọ siwaju awọn ijoye, nitoripe bi o ti wu ki o ri, on ko fi owo sinu ladugbo nitorina yio şajeji fun lati ro wipe on le ri owo ninu rę.

O fi igboiya mu owo yi lọ si iwaju awọn ijoye, o si jewọ fun wọn bi on ti şe ri owo na. Lęsękese, awọn ọlọpa Ọba ti ki i mọlę, nwọn si fi ohun şọkan wipe Ọmọbọla ji ọkę męrin owo yi ni. Şugbọn nigbati o şakiyesi pe oju ti ka on mọ ni o wa şe ijewọ yi. Iyawo rę tun gbo, o bęręsi bu u pe, olori buruku, alakori, olosi ati oniruru ọrọ kobakungbe ni o bęrę si sọ fun un.

laipę, nwọn ti i mọle nwọn si mu u lọ si iwaju awọn ijoye. Nigbati awọn ijoye ri Ọmọbọla ti nwọn si gbọ gbogbo ohun ti o şelę, nwọn si iranti asọtęlę Ifa ti o wipe "Aponmi-ta, aruladugbo ni yio ję ọba fun wọn". Lęsękese, nwọn paşę lati da Ọmọbọla silę ki o ma a lọ si ile rę, nwọn si kilọ fun un wipe ko gbọdọ fi ilu silę fun ọjọ medogun.

Ọmọbọla wa yipada, o dorikę ọna ile, iyawo rę mbu u ni abutọna bi ti nwọn ti nlọ on paapa si nsun ękun kikoro. Fun ọjọ mędogun iyawo rę ko fi onje lọ o, ohun ti o ba ri funra rę ni o nję şugbọn nibati ọjọ yi pe, nwọn ran awọn ọlọpa męrin lati lọ mu u Ọmọbọla wa lati ile rę.

Şugbọn fun iyalęnu nlanla, nwọn wi fun Ọmọbọla pe on ni Ifa mu lati ję ọba, nwọn si mu u lọ si Iledi nitori iwa otitọ ọkan rę. Irohin kan iyawo rę ni ẹnu agbala ile Ọba wipe, ọkọ rę ni nwọn mu lati fi ję Ọba, ko si gbagbọ titi ti nwọn fi bęręsi lu ilu Ọba fun un. Bayi ni Ọmọbọla "Bi ori ba pę n'ilę a d'ire şe di ọba ilu.

Irohin tun kan oloko ọjọ kini ti o ti nsingba lọdọ rę pe Ọmọbọla ti di Ọba ni ilu keji ti o binu lọ, o mura lati wa ki Ọmọbọla ati lati wa wadi otitọ ti o wa ninu ọrọ na. Şugbọn nigbati o de agbala Ọba, Ọmọbọla "Bi ori ba pę n'ilę a d'ire" ti o si ri i daju pe on ni nwọn fi ję ọba nitotọ, o wo oke, o wo ilę, o si wi pęlu omije loju pe, "Nitotọ ni oriki rę "Bi ori ba pę n'ilę a d'ire".

Ohun pataki ti a şe akiyesi lara oloko yi ni wipe, ohun gbogbo ti rehin fun un, ęwu akisa ni o wọ s'ọrun, inu ahere ni o tun pada si lati ma a gbe. Ọba wo o pęlu iyanu nla o si paşe pe ki nwọn fun un ni iparọ aşọ marun. O wi pęlu iyanu wipe "Nitotọ ni oriki mi. Bi ori be pę n'ilę a d'ire".

Olotu mo dupę aye ti e gba mi.

# Adajọ ni ki awọn ęlęwọn meji tun lọ şe ęwọn ọdun męsan

IBADAN.

Ni ọjọ 'Ru ti işe ọjọ kewa oşu yi ni Ogbęni Kester Adajọ Kotu kekere kan ni Ibadan ri i pe awọn ęlęwọn meji, Idowu Ọbasanya ati Jimọ Iyadan, ọkọọkan wọn si nlọ ęwọn ọdun męsan lọwọ ni Abęokuta, jębi ęsun miran ti awọn ọlọpa kasi wọn lorun pe, nwọn ji mọto akero (taxi car) kan ati awọn gallọnu epo mọto męwa ni o ba ni ki nwọn lọ şe ęwọn ọdun męrin-abọ, męrin-abọ.













Awọn koro "Multivite" ni egbogi adęra "A, B, C, ati D" ninu, eyiti olukuluku fę lati fi kun ilera ati okun agbara ti o jọju




BDH THE BRITISH DRUG HOUSES LTD.

PRODUCT Distributed by branches of THE UNITED AFRIC... O. OF NIGERIA LTD.

# Awọn Ọlọṣa Idi-araba Mushin lọ f'ọle Al'bẹokuta

ABẸOKUTA.

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Adajọ Koti Ake (Ake Grade 'A' Court) Abẹokuta ju awọn ọlọṣa meji kan Isiaka Maiduguri eni odun mẹtadinlọbon ati Mustafa Maiduguri eni odun mẹdogbon sẹwọn ọdun marunmarun nigbati nwọn jebi ẹsun ole jija.

Ejọ ti awọn ọlọpa ba awọn odaran na ro nipe nwọn lo fọ ile Ọgbẹni kan ti njẹ Sunmọla ni ni Agọ-Ika ni alẹ ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kokandinlogun oṣu kẹsan ọdun yi, nwọn si ji ọpọlọpọ ẹwu ti aropọ owo rẹ jẹ ponun mejila ṣile mẹta (£12 3s.) ko nibẹ. Nwọn ni ara awọn ọlọṣa ti o nwa lati Idi-Araba l'ẹba Mushin wa gbogun ti ilu Abẹokuta ni awọn odaran mejeji yi.





Gbigbona tabi Tutu

O nṣiṣẹ miran lẹhin isọ ara dọtun

GUINNESS nfun ni ni Ilera ati Okun


# Ọjẹwale ọrun're

OGBOMOSHO.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ogbonjọ oṣu kokanla odun yi ni alagba Olahan Atanda Ọjẹwale ṣe alaisi ni ile rẹ, ni agboile Alaake, Oke Mọsifa, Ogbomọsho. Pẹlu eye ni gbogbo ebi ati ojulumọ fi lọ sin oku rẹ ni ọjọ keji, awọn ọmọ oku na Moses Popoola Ọjẹwale; Shittu Ọjẹwale, Gboyega Ọjẹwale; Lasisi Alabi Ọjẹwale; Abioye Ọjẹwale; Rabi S. Arẹmu; Tanilegbọla Ọjẹwale ati Rafatu Ọjẹwale si fi jije ati mimu te gbobo enia lọrun.

Ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejila oṣu kejila odun yi ni Ọgbẹni S. L. Ọjẹwale ti iṣe aburo ologbe na ti o wa ni Accra Ghana beresi se inawo ti oku na nibati o ti Accra de, o si nawo gbaku-gbiyan. Irohin ko to afojuba ni inawo ti Ọgbẹni S. L. Ọjẹwale na ṣe. Beni awọn Alakẹ Ọjẹwale, Ṣubuọla Ọjẹwale, Dọla Ọjẹwale ati Ṣubulade Ọjẹwale ti nwọn jẹ aburo ologbe na si nawonara ri ibi oku na.

Ọgbẹni Amodu Dogo, Onilu Apala ni o wa ṣere fun won nibi oku na, o si fi ilu rẹ dabira nibẹ fun awon onijo. Die ninu awọn enia pataki-pataki ti aye wa lati daruko ti o wa si ibi eye isinku na ni Kansilo Shittu Adegboye, awon Iyaafin Muniratu, Arinọla, awọn Ọgbẹni Ade. Adeyẹmọ, Kafinta; Gbadamosi Aderinto, Samuel Adewale Onilu Yoruba, Daniel Ogunrinde, Jacob Adeniyi, Karimu Idowu, Emmanuel Ladeji, Moses Okunade ati Joseph Ayanwọla.

Ehin oku a dara o.


Fun ẸSANRI
ati
AKỌ IBA
mu
PHENSIC




Wa a gbadun, ni kiakia, bi o ba mu Phensic. Egbogi ti o darajulọ fun iwosan ti a ni ni. Fun iba, otutu, esanri ati otutu-ayọkẹlẹ—mu Phensic. Ri i daju pe o ni Phensic lọwọ ninu ile nigbagbogbo.




PHENSIC

Lagbarajü—o yara ṣiṣẹ ju o si dara ju Aspirin nikan lọ

**The truck for BIG loads!**

Mọto MORRIS oni tọnun meje ko gbogbo agbara miran papọ gẹgẹbi awọn anfani ti o wa ninu ṣiṣe rẹ



MORRIS 701 DIESEL

Mọto akẹru ti o dara julọ niyi fun awọn ẹru ti o ba tobi gidi. Ọpọlọpọ awọn anfani rẹ nlanla ni. Agbara fun owo mọto lati wa a ni irọrun, agbara fun ijanu ti o daju, ikoko ti o gba epo pupọ fun irinajo jijinna ati aye irọrun fun awa-mọto. Wonyi jẹ diẹ ninu anfani ti o mu ki mọto na fi darajulọ lati fi ẹru ṣọwọ pẹlu ẹndinwo.

Ranṣẹ fun un nisisiyi lati ọdọ C·F·A·O ni sakani Ile Iṣẹ Mọto

AWỌN ẸKA RẸ WA NI: LAGOS · APAPA · IBADAN · KANO · JOS · ENUGU · ONITSHA · ABA

## Igbeyawo Israel minringindin

AGBEYE OSHOGBO.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni Ọgbẹni Israel Faniyi gbe Omidan Omoronikẹ Awẹkẹ ni iyawo, irohin ko to afojuba ni ẹyẹ igbeyawo na jẹ, ẹbi t'ọkọ t'aya ni o rawo nara nibi aṣeyẹ na, nwọn fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Taiye Adigun, Asiru Agboola, I. B. Idowu, N. O. Oyedokun, T. Olawale, S. O. Olagunoye, L. O. Egbebi, R A Lagunju, Karimu Driver ati awọn Omidan Aminatu Ajile ati Lydia Owolabi

Ki Oluwa ṣe iyawo ni abiyamọ, ki O si fi irẹ kari o. Amin.

## Ẹka ẹbgẹ Afẹnifẹre Ijaw ni igbẹkẹle si Awolọwọ

ALEIBIRI.

LENLỌLỌYI ni ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre (ACTION GROUP) Ijaw, Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe ipade pataki kan fun ọjọ meji. Nwọn ṣe ipinnu ninu ipade na pe, awọn ni igbẹkẹle gan an si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati gbogbo awọn isọngbe rẹ ti nwọn lọ ba wọn ṣe Ipade Londọnu ti nwọn ṣe gbẹhin yi, nwọn sọ pe awọn gbadun iṣẹ ribiribi ti awọn iko ẹgbẹ na fi gbobo ara wọn ninu Ipade Londọnu na pupọ.

..igbagbogbo ni o ngbẹhin ninu ipo ẹkọ ile-iwe






FERBELAN jẹ egbogi atẹlẹṣẹ ti a fi ọgbọn ijinlẹ popọ pẹlu onjẹ adẹra ti o peyejulọ ati ohun mimu ti o ṣe pataki fun ilera atata ati ilosiwaju awọn ọmọ rẹ.

A BDH PRODUCT

**FERBELAN** Trade Mark

THE BRITISH DRUG HOUSES — LONDON



Awọn alagbata egbogi na ni Kingsway Chemists, o si tun wa ni awọn Ile-egbogi pataki pataki miran.

**OSTERMILK**

njẹki ọmọ-ọwọ nitẹlọrun ! Iagbara ! Iokun ninu !



Iya ko le fun ọmọ-ọwọ l'onjẹ mọ, ọpọlọpọ ...... wara Ostermilk. Ostermilk, wara ti o dara lonjẹ, o le mu ki ọmọ-ọmọ rẹ lagbara ki o si ni itẹlọrun pẹlu. O ni afikun onjẹ okun-inu pupọ (extra vitamin—extra iron). Maṣe daamu, Ostermilk ma a nwa ni akolun pẹ ju wara lasan lọ—nitori nwọn nde agolo rẹ pa dada. Sa ti fi omi po Ostermilk——fun ọmọ-ọwọ mu——wa a si ri ọmọ na ti yio ma a rẹrin muṣẹ-muṣẹ.

**OSTERMILK**

MADE BY GLAXO LABORATORIES LTD., GREENFORD, ENGLAND

Agent: R. E. HARDING AND CO. LTD., 28 COMMERCIAL AVENUE, YABA, LAGOS AND ALSO PRIVATE MAIL BAG, ABA.

